# IGBESI-AYÉ ONIGBAGBỌ́

**Romu 12:1-21; 2 Peteru 1:5-11**

**ẸKỌ 357 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Nitorina mo fi iyọ́nu Ọlọrun bẹ̀ nyin, ará, ki ẹnyin ki o fi ara nyin fun Ọlọrun li ẹbọ ãye, mimọ́, itẹwọgbà, eyi ni isẹ-isin nyin ti o tọ̀na" (Romu 12:1).**

**I Irin Onigbagbọ́ Ninu Ayé**

1 Eniyan Ọlọrun gbọdọ kún fún iṣẹ́ ṣiṣe ti o li ere fun Ọlọrun, Romu 12:1, 11-13; Luku 19:12-27; Jakọbu 1:27

2 Igbesi-ayé Onigbagbọ́ ní lati bá ti Kristi mu, kò gbọdọ fara wé àṣà, ihuwasi, tabi ẹmi ti ayé yii, Romu 12:2; Johannu 17:14; 2 Kọrinti 6:17, 18; 7:1; Ifihan 18:4

3 Ohun pataki ju lọ ti a n beere ninu igbesi-ayé Onigbagbọ́ ni pe ki o mọ aipe rẹ̀ ki o si maa ṣiṣẹ rẹ̀ gbogbo pẹlu igbona ọkàn gẹgẹ bi ipe rẹ̀, Romu 12:3-8; Owe 25:27; 1 Kọrinti 12:11-27; Efesu 4:1-13

4 Awọn iwa ti o maa n so igbesi-ayé Onigbagbọ́ ró ni ifẹ́ ará, ifẹ inurere si eniyan gbogbo ati iṣoore, Romu 12:9, 10, 14-16; 13:9, 10; Matteu 22:37-40; 1 Kọrinti 13:1-13; 2 Peteru 1:5-11

5 Onigbagbọ́ ni lati maa fi ofin nla ti Ihinrere ṣe iwa hù, eyi ti Jesu Kristi ṣe apẹẹrẹ rẹ̀ ninu igbesi-ayé Rẹ̀; "Maṣe jẹ ki buburu ṣẹgun rẹ, ṣugbọn fi rere ṣẹgun buburu," Romu 12:17-21; Orin Dafidi 64:1-10; 94:1, 23; Matteu 5:38-48

## ALAYE

**Irin Onigbagbọ́ Ninu Ayé**

Ki ni igbesi-ayé Onigbagbọ́? Ni kukuru, itumọ rẹ̀ ni wiwà laaye fun ogo Ọlọrun, ki a maa lo ara wa si ipa Kristi, ki a si jẹ́ iwe Rẹ̀ ti gbogbo eniyan mọ̀ ti wọn si n kà. Awọn Onigbagbọ́ jẹ aṣoju Ijọba Ọlọrun, ikọ̀ fun Kristi, nipasẹ awọn ẹni ti Ọlọrun n bẹ gbogbo ayé lati bá Oun laja nipa Kristi (Ka 2 Kọrinti 5:19, 20).

Awọn Onigbagbọ́ ni lati jẹ́ imọlẹ ninu ayé (Filippi 2:15), ati apẹẹrẹ oore-ọfẹ Ọlọrun ti n yi ọkan pada. Bi a kò ba le dá awọn ti o jẹwọ titẹle Kristi mọ̀ nipa igbesi-ayé iwa mimọ́ wọn, ki a si mọ̀ wọn fun iyara-ẹni-sọtọ wọn kuro ninu ayé, yoo ṣoro ki wọn to le jẹ Onigbagbọ́.

Iyara-ẹni-sọtọ kuro ninu ayé jẹ ohun ti isin Kristi ati igbesi-ayé Onigbagbọ́ n beere lọwọ ẹni. Ọkàn Onigbagbọ jẹ́ ti Oluwa, oun si jẹ́ ọmọ ibilẹ Ijọba Ọlọrun. Onigbagbọ wà ninu ayé ṣugbọn ki i ṣe ti aye; oun jẹ́ alejo ati arin-rin-ajo ninu rẹ̀ (Ka 1 Kọrinti 5:9-11; Heberu 11:13).

Ki ni ayé jẹ́ ti Onigbagbọ fi gbọdọ ya ara rẹ̀ kuro ninu rẹ̀? Ọrọ Ọlọrun tọka si gbogbo eto, gbogbo eniyan, gbogbo ẹmi ti o ba lodi tabi ti o tako ofin Ọlọrun ati Ihinrere Jesu Kristi gẹgẹ bi "ayé." Lati jẹ́ apakan ayé tabi ki a wà ni iṣọkan pẹlu igbekalẹ ati eto rẹ̀, ni lati wà ni ọta si Ọlọrun. C. H. Spurgeon, iranṣẹ Ọlọrun pataki ni igba kan ri, sọ nipa ayé pe: "Ninu eto rẹ̀ mẹsan-an ninu mẹwaa ni o jẹ́ iró, ọ̀kan ti o kù jẹ́ imọ-ti-ara-ẹni-nikan; ati ọ̀kan-ṣoṣo naa paapaa ni iró ni isalẹ rẹ̀." Ọrọ Ọlọrun sọ pe: "ẹnyin panṣaga ọkunrin, ati panṣaga obirin,ẹ kò mọ̀ pe ibarẹ́ aiye iṣọta Ọlọrun ni? nitorina ẹnikẹni ti o ba fẹ lati jẹ́ ọrẹ aiye di ọtá Ọlọrun" (Jakọbu 4:4). Pe otitọ ni ọrọ̀ yii hàn gbangba ninu akọsilẹ Ọlọrun: "Awọn ọba aiye dide, ati awọn ijoye kó ara wọn jọ si Oluwa, ati si Kristi rẹ̀" (Iṣe Awọn Apọsteli 4:26). Aṣẹ Ọlọrun fun olukuluku ti yoo maa pe orukọ Kristi ni eyi: "Ẹ jade kuro larin wọn, ki ẹ si yà ara nyin si ọtọ, li Oluwa wi, ki ẹ máṣe fi ọwọ́ kàn ohun aimọ́; emi o si gbà nyin. Emi o si jẹ Baba fun nyin, ẹnyin o si jẹọmọkunrin mi ati ọmọbirin mi, li Oluwa Olodumare wi" (2 Kọrinti 6:17, 18). Bi o tilẹ jẹ pe awọn ẹsẹ Iwe Mimọ wọnni ní itumọ ti o yanju, sibẹ ọ̀pọlọpọ ni o wà ninu ayé ti n fẹ́ ní ojurere Ọlọrun ti wọn si tun n fẹ jẹ́ ọrẹ ayé. Irú awọn eniyan bẹẹ n fẹ ojurere Ọlọrun ṣugbọn wọn kò lè ru ẹ̀gàn Ihinrere tabi fi ara da iyà Agbelebu (Ka Galatia 5:11; Matteu 11:6; 13:21).

**Ẹbọ Aayè**

Ẹkọ pataki miiran ti Ihinrere ati ti Isin Kristi ni pe ọmọ-lẹyin Jesu gbọdọ jọ̀wọ́ gbogbo ayé rẹ̀ fun isin ati ipè Ọlọrun. Aṣayan ẹkọ wa sọ pe fifi aye wa bi ẹbọ aaye, mimọ́ ati itẹwọgba fun Ọlọrun ni iṣẹ-isin wa ti o tọna.

Kristi ni olori ifẹ ọkan ati alagbara lori igbesi-ayé Onigbagbọ́. Bi o tilẹ jẹ pe ohun pupọ ati awọn eniyan ni o le ni ipá lori igbesi-aye eniyan, ati awọn Onigbagbọ pẹlu, sibẹ bi Kristi ati Ijọba Ọlọrun kì i ba ṣe koko ohun ti o n ṣe akoso igbesi-aye eniyan kan, iru ẹni bẹẹ ki i ṣe Onigbagbọ́. Gẹgẹ bi oorun ti

duro ti ayé si n yi i po, ti o si n gba ooru ti o n mu ẹ̀da wa laaye ati imọlẹ lati inu “ina ileru” rẹ̀, bẹẹ gẹgẹ ni igbesi-ayé Onigbagbọ́ ni lati maa yi Kristi po, ki o si maa gba agbára ti ẹmi ati imọlẹ lati ọdọ Rẹ̀.

Ọlọrun n fẹ ki ọwọ́ awọn eniyan Oun kún fun iṣẹ Rẹ̀. Ọwọ́ awọn eniyan ayé kún pupọ fún wiwá erè ti ara wọn, lilepa opin rere fun ara wọn, wọn wa laaye fun ara wọn, ati fun anfaani ti ara wọn. Onigbagbọ́ wà laaye fun Kristi. O n wá itẹsiwaju ohun ti iṣe ti Kristi dipo ti ara rẹ̀, o si jẹ́ alabaṣiṣẹpọ pẹlu Ọlọrun, ki i ṣe ohun igba isisiyii nikan ni o n lepa bi kò ṣe pe fun ayeraye pẹlu! (Wo 1 Kọrinti 3:9). Bi ko ṣe pe eniyan ba wa laaye fun Oluwa, yoo jẹbi ayeraye yoo si di ẹni itanu. Lati ri talẹnti ẹni mọlẹ ni lati ṣe bi awọn eniyan ayé ti n ṣe, awọn ti kò wá ohun ti Ọrun ti wọn si n fi tori tọrun wọn wá nnkan ayé (Ka Matteu 25:14-30).

**Yiyipada**

“Ẹ má si da ara nyin pọ̀ mọ́ aiye yi: ṣugbọn ki ẹ parada lati di titun ni iro-inu nyin.” Iyè jẹ́ ilẹkun sinu ọkàn; a kò si le sọ ọ ju bi o ti ṣe pataki to pe ki awọn Onigbagbọ́ fi ero wọn sọdọ Kristi ati si ipa ti Ijọba Rẹ̀, ki wọǹ má si maa rò nipa ayé ati ohun ti ó wà ninu ayé. Ayé ti jinna si Ọlọrun to bẹẹ gẹ ti o fi jẹ pe gbogbo ọna ti eniyan mọ̀ ni o fi n polowo ẹ̀ṣẹ ati ohun gbogbo ti n sún ni dá ẹ̀ṣẹ. Pupọ ninu ọ̀na idaraya ti awọn eniyan ti dá silẹ ni o lumọ ẹ̀ṣẹ, ni o yatọ si ti ẹda, ti o si mú iwa ibajẹ lọwọ pẹlu. O jẹ́ ohun ti n pa ọkàn run nitori pe o maa n sún eniyan dẹṣẹ.

Onigbagbọ tootọ kò ni ifẹ tabi akoko fun ohun gbogbo ti a n fi ẹ̀tan pe ni igbadun. Ẹrọ tẹlifiṣọn jẹ ọ̀kan ninu awọn ohun titun ti awọn eniyan ṣẹṣẹṣe; ti awọn eniyan ti kò nilaari ti sọ di ibajẹ to bẹẹ ti o fi jẹ pe ọ̀kan ni ninu awọn ohun ti o lewu ju lọ fun igbesi-ayé Onigbagbọ ti awọn ọdọ dojukọ lonii. Awọn ile-iṣẹ ọti ati taba jẹ́ onigbọwọ meji pataki fun tẹlifiṣọn wíwò, owo gọbọi ni wọn si n ná lọdọọdun lati maa polowo ọja wọn. Njẹ ẹnikẹni tun ṣẹṣẹ le maa wadii pe “Njẹ Onigbagbọ́ le mu taba tabi ọti?”

**Irẹlẹ**

Igberaga -- wíwa ti ara ẹni, gbigbe ara ẹni ga – ni i ṣe gbongbo ohun ti o fa iṣubu Satani, ati ti ailonka ọmọ-eniyan lati igba naa. Idakeji ilepa ti ara bẹẹ ni irẹlẹ. A kò le ya irẹlẹ nipa kuro ninu Ihinrere Jesu Kristi. Ori ẹkọ naa ka pe: “Njẹ mo wi fun olukuluku enia ti o wa ninu nyin, nipa ore-ọfẹ ti a fifun mi, ki o máṣe rò ara rẹ̀ jù bi o ti yẹ ni rirò lọ; ṣugbọn ki o le rò niwọntunwọnsi, bi Ọlọrun ti fi iwọn igbagbọ́ fun olukuluku.” Siwaju si i, “niti ọlá, ẹ mã fi ẹnikeji nyin ṣaju.”

Onigbagbọ́ maa n fẹ lati dabi Oluwa rẹ̀. O maa n fẹ ki igbesi-ayé oun fi ara pamọ sẹyin Agbelebu Kristi, pe ki ẹwa Jesu le maa tàn jade. Ọlọrun sọ pe “Ẹ ni ero yi ninu nyin, eyi ti o ti wà pẹlu ninu Kristi Jesu: Ẹniti o tilẹ jẹ aworan Ọlọrun, ti kò ka a si iwọra lati ba Ọlọrun dọgba: Ṣugbọn o bọ́ ogo rẹ̀ silẹ, o si mu awọ̀ iranṣẹ, a si ṣe e ni awòran enia. Nigbati a si ti ri i ni iri enia, o rẹ̀ ara rẹ̀ silẹ, o si tẹriba titi di oju ikú, ani ikú ori agbelebu” (Filippi 2:5-8). Ọpọ eniyan ni o wà ti wọn n wi pe kò ṣe e ṣe fun eniyan lati gbé igbesi-ayé ti a le fi wé ti Kristi. Awọn oniyemeji ati awọn alahesọ le sọ ohunkohun ti wọn ba fẹ́, ṣugbọn Jesu fi apẹẹrẹ lelẹ fun gbogbo eniyan lati tẹle. O di ara O si n ba wa gbé, awọn eniyan nipa oore-ọfẹ Ọlọrun, le gbé igbesi-ayé mimọ́, ailẹṣẹ, ti o si wu Ọlọrun.

**Siso Eso**

Idalare a maa kan “ogbologbo ọkunrin nì” mọ agbelebu Kristi. (Wo Romu 6:1-7). Isọdimimọ́ a maa pa “ogbologbo ọkunrin naa” kú patapata; a tu gbongbo ẹ̀ṣẹ kuro, iwa mimọ́ a si kún igbesi-ayé Onigbagbọ naa (Wo Luku 1:74, 75; Efesu 5:27). Nigba ti a ba si fi agbára Ẹmi Mimọ ati ina wọni, Ẹni Ikẹta ninu Ọlọrun Mẹtalọkan yoo bẹrẹ si i tọ́ ni “sinu otitọ gbogbo,” agbára itọni ati iṣamọna yii ni igbesi-ayé eniyan yoo jẹ́ ki Onigbagbọ́ naa le so eso pupọ (Wo Johannu 16:13; 15:8).

Kristi ni Ajara tootọ; awọn Onigbagbọ́ si ni ẹka. Irú eso ti Ajara n so ni awọn ẹka paapaa n so. Nitori naa ni awọn Onigbagbọ́ ṣe n so iru eso kan naa ati ṣe iru iṣẹ rere kan naa niwaju awọn eniyan gẹgẹ bi Jesu Kristi ti ṣe (Ka Johannu 14:12; 15:1-8).

Igi kekere eleso yoo bẹrẹ si i so eso ni iwọnba ti rẹ̀ lati kekere. Bi o ti wù ki eso naa le kere tó, eso ti o n so dara gẹgẹ bi yoo ti maa ri titi. Bi ọdún ti n yi lu ọdún, ti igi naa si n dagba, bẹẹ ni yoo maa so eso pupọ si i, ṣugbọn eso naa yoo jẹ́ irú kan naa ti o ti n so lati ibẹrẹ. Ninu bi eso naa ti pọ to ni iyatọ gbé wà -- ṣugbọn kò si iyatọ ninu iru eso ti o n so tabi didara rẹ̀. Bẹẹ gẹgẹ ni igbesi-ayé Onigbagbọ́ ṣe bẹrẹ. O bẹrẹ si i so eso ni iwọnba kekere nipa ti ẹmi, ṣugbọn eso ti ẹmi ni o n so. Bi Onigbagbọ́ ti n dagba si i ninu oore-ọfẹ ati imọ̀ Oluwa Jesu Kristi, wọn a maa so ọ̀pọlọpọ eso ti Ẹmi Ọlọrun, ṣugbọn irú eso kan naa ni iṣe; kiki pe eso naa pọju ti atẹyinwa ni. A ṣe alaye didagba ninu oore-ọfẹ lọna ti o dara ninu ẹkọ wa: “Ati nitori eyi nã pãpã, ẹ mã ṣe aisimi gbogbo, ẹ fi iwarere kún igbagbọ́, ati imọ kún iwarere; ati airekọja kún imọ, ati sũru kún airekọja; ati iwa-bi-Ọlọrun kún sũru; ati ifẹ ọmọnikeji kún iwa-bi-Ọlọrun;

ati ifẹni kun ifẹ ọmọnikeji.  Nitori bi ẹnyin bá ni nkan wọnyi ti nwọn bá si pọ̀, nwọn ki yio jẹ ki ẹṣe ọ̀lẹ tabi alaileso ninu ìmọ Oluwa wa Jesu Kristi.”

A le sọ pe titi lọ ni Onigbagbọ́ maa n fi iwa rere ati ẹwa ti ó wà ninu Oluwa wa Jesu Kristi kún igbesi-ayé rẹ̀.  Bi Onigbagbọ́ ti jẹ ẹka lara Ajara Tootọ, o n gba oje, ti i ṣe iwà mimọ́, ti i ṣe orisun iye fun ọkan, bẹẹ ni o n fi awọn oore-ọfẹ Kristi kún igbesi-ayé rẹ̀.

**AWỌN IBEERE**

1 Ki ni koko iṣẹ Onigbagbọ?

2 Ki ni ṣe ti Onigbagbọ kò fi gbọdọ ni idapọ pẹlu ayé?

3 Tumọ ohun ti Bibeli pe ni “ayé”?

4 Bawo ni eniyan ṣe le mọ awọn Onigbagbọ́ yatọ si awọn eniyan ayé?

5 Ki ni ṣe ti kò fi tọna fun Onigbagbọ́ lati ni ipá ninu pupọ ninu eré idaraya ayé?

6 Darukọ diẹ ninu iwa rere igbesi-ayé Onigbagbọ́.

7 Ki ni itumọ ẹsẹ Iwe Mimọ́ ti o wi pe Kristi ni Ajara ati awọn Onigbagbọ́ ni ẹ̀ka?

8 Ṣe apejuwe bi awọn Onigbagbọ́ ṣe le maa so eso si i ninu igbesi-ayé wọn.